Ábúráhámù Di Ọ̀rẹ́ Ọlọ́run

JẸ́NẸ́SÍSÌ 12:1-9; 18:1-19; 22:1-18

JÈHÓFÀ NI **ÁBÚRÁHÁMÙ** ÀTI **SÁRÀ*** Ń SÌN, ÌLÚ ÚRÌ NI WỌ́N SÌ Ń GBÉ.LỌ́JỌ́ KAN, **JÈHÓFÀ** BÁ ÁBÚRÁHÁMÙ SỌ̀RỌ̀.

LỌ SÍ ILẸ̀ TÍ MÀÁ FI HÀN Ọ́, MÀÁ SÌ SỌ Ọ́ DI **ORÍLẸ̀-ÈDÈ ŃLÁ.**

*ÁBÚRÁMÙ ÀTI SÁRÁÌ NI WỌ́N Ń JẸ́ TẸ́LẸ̀.

KÍ NI JÈHÓFÀ SỌ FÚN YÍN?

Ó NÍ KÁ **KÓ KÚRÒ** NÍBÍ. A MÁA NÍ LÁTI FI **ÀWỌN ỌRẸ́** WA ÀTI **ÀWỌN MỌ̀LẸ́BÍ** WA SÍLẸ̀.

OHUNKÓHUN TÍ **JÈHÓFÀ** BÁ NÍ KÁ ṢE NI MÀÁ ṢE.

ÁBÚRÁHÁMÙ AND SÁRÀ KÚRÒ NÍ ÚRÌ, ÀMỌ́ WỌN Ò MỌ **IBI** TÍ WỌ́N Ń LỌ . . .

. . . BẸ́Ẹ̀ SÌ RÈÉ, **WỌN Ò BÍMỌ,** BÁWO WÁ NI ÁBÚRÁHÁMÙ ṢE MÁA DI **ORÍLẸ̀-ÈDÈ ŃLÁ?**

www.jw.org © 2017 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

NÍGBÀ TÍ ÁBÚRÁHÁMÙ PÀGỌ SÍ MÁMÚRÈ, Ó RÍ **ÁŃGẸ́LÌ** MẸTA TÍ WỌN DÀ BÍ ÈÈYÀN.

Ẹ JỌ̀Ọ́, Ẹ DÚRÓ BÁ WA **JẸUN.**

Ó YÁ! LỌ ṢE **BÚRẸ́DÌ,** ÈMI Á LỌ PA **ẸRAN** FÚN ÀWỌN ÀLEJÒ WA.

LÁÀÁRÍN ỌDÚN KAN, **SÁRÀ MÁA BÍ ỌMỌKÙNRIN KAN.**

ÈMI ÀTI ÁBÚRÁHÁMÙ TI **DÀGBÀ JÙ LÁTI BÍMỌ!**

KÍ LÓ DÉ TÍ SÁRÀ FI **RẸ́RÌN-ÍN?** ṢÉ OHUNKÓHUN WÀ TÓ LE JÙ FÚN **JÈHÓFÀ** LÁTI ṢE NI?

ÀNÍ O RẸ́RÌN-ÍN!

MI Ò RẸ́RÌN-ÍN O!

JÈHÓFÀ MÁA ṢE OHUN TÓ ṢÈLÉRÍ, O SÌ MÁA DI **ORÍLẸ̀-ÈDÈ TÓ TÓBI, TÓ SÌ LÁGBÁRA.**

www.jw.org © 2017 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

BÍ ỌLỌ́RUN ṢE ṢÈLÉRÍ, SÁRÀ BÍ ỌMỌKÙN RIN KAN, **ÍSÁKÌ** LORÚKỌ RẸ. ÁBÚRÁHÁMÙ **NÍFẸẸ́** RẸ, ÍSÁKÌ SÌ DÀGBÀ DI **ẸNI TÓ NÍFẸẸ́ JÈHÓFÀ.**

NÍGBÀ TÓ YÁ, JÈHÓFÀ DÁN ÁBÚRÁHÁMÙ WÒ, Ó NÍ KÍ ÁBÚRÁHÁMÙ FI ÍSÁKÌ **RÚBỌ.**

Ó **NIRA GAN-AN** FÚN ÁBÚRÁHÁMÙ LÁTI ṢE OHUN TÍ JÈHÓFÀ ṢỌ, ÀMỌ́ ÒUN ÀTI ÍSÁKÌ **GBẸ́KẸ̀ LÉ JÈHÓFÀ.**

DÚRÓ!

ÌGBÀ YẸN NI JÈHÓFÀ WÁ MỌ PÉ **ỌRẸ́ TÓ JẸ́ ADÚRÓṢINṢIN** NI ÁBÚRÁHÁMÙ, TORÍ NÁÀ, Ó DÁ ỆMÍ ÍSÁKÌ SÍ, Ó SÌ MÚ KÍ ÀWỌN ỌMỌ ỌMỌ ÁBÚRÁHÁMÙ DI ORÍLẸ̀-ÈDÈ ÍSÍRẸ̀LÌ.

KÍ LA RÍ KỌ́ NÍNÚ ÌTÀN YÌÍ?

ÌGBÀ WO LÓ **NIRA** FÚN ÁBÚRÁHÁMÙ LÁTI ṢÈGBỌRÀN SÍ JÈHÓFÀ?
AMỌ̀NÀ: JẸ́NẸ́SÍSÌ 12:1; 22:1, 2.

BÁWO NI ÁBÚRÁHÁMÙ ṢE DI **ỌRẸ́ ỌLỌ́RUN?**
AMỌ̀NÀ: JẸ́NẸ́SÍSÌ 26:5; HÉBÉRÙ 11:8-10, 17.

BÁWO **LO** ṢE LÈ DI ỌRẸ́ ỌLỌ́RUN?
AMỌ̀NÀ: SÁÀMÙ 15:1-5.

www.jw.org © 2017 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania